# Yoruba Paper 2,May/June. 2012

**Question 1**
**<u>SECTION A: EDE</u>**
***Kọ  àròkọ tí kò dín ní 300 ẹyọ ọ̀rọ̀ lórí orí-ọ̀rọ̀ kan ṣoṣo tí o bá yàn.***

1. ***Ìṣẹ̀lẹ̀ búburú kan tí n kò lè gbàgbé láéláé.***
2. ***Iṣẹ́ lòògùn ìṣẹ́.***

***(d)     Ọjà kan ní agbègbè mi.***

1. ***Ìwé kíkà dára ju iṣẹ́ kíkọ́ lọ.***

***(e)     Kọ lẹ́tà sí ẹ̀gbọ́n rẹ tí ó wà ní ilẹ̀ òkèèrè láti ṣe àlàyé ìgbáradì tí o ń ṣe fún ìdánwò àṣekágbá rẹ kí o sì béèrè ìrànwọ́ nípa àwọn ohun tí o nílò.***

**Question 2**
**SECTION A: EDE**
***Mú márùn-ún nínú àwọn ọ̀nà ìṣẹnupè kọ́ńsónántì Yorùbá kí o sì ṣàlàyé ọ̀kọ̀ọ̀kàn wọn.***

**Question 4**
**SECTION A: EDE**
***Fa àpólà àpọ́nlé yọ nínú ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn gbólóhùn wọ̀nyí kí o sì sọ oríṣìí àpọ́nlé tó jẹ́:***

1. ***Adéagbo sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ìrẹ̀lẹ̀.***
2. ***Jùmọ̀kẹ́ ń rìn bí aláìsàn.***
3. ***Màá lọ sí oko.***
4. ***Bùkọ́lá hùwà rere nítorí ọjọ́ àtisùn.***
5. ***Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wà ní kíláàsì.***

**Question 5**
**SECTION A: EDE**
**(a)** ***Fa atọ́ka àsìkò àti ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ inú ọ̀kọ̀ọ̀kan gbólóhùn wọ̀nyí yọ:***

1. ***Wọ́n máa gbọ́ nípa ọ̀rọ̀ náà.***
2. ***Ọ̀gá ń bínú sí akẹ́kọ̀ọ́ náà.***
3. ***Bí wọ́n bá sọ bẹ́ẹ̀, wọ́n ti ba nǹkan jẹ́.***
4. ***Wọ́n á wá.***
5. ***Ṣọlá máa ń pọn omi tà.***

***(b) Sọ irúfẹ́ àsìkò/ibá-ìṣẹ̀lẹ̀ tí atọ́ka kọ̀ọ̀kan fi hàn.***

**Question 7**
**SECTION B: LITIRESO**
***Ṣàlàyé ohun tí ẹsẹ ifá ìsàlẹ̀ yìí dá lé.***

***"Fílàní méjì ń jà n'ísàlẹ̀ àbàtà, irábá irábá;***
***Fílàní méjì ń jà n'ísàlẹ̀ àbàtà, iràbà iràbà;***
***A diá fún ọba Àjànà,***
***Tí ń lọ dá'dìí àbíkú …"***

**Question 8**

**SECTION B: LITIRESO**

***Ṣàlàyé ipa tí Àǹséétù kó  nínú ìgbésí-ayé Ọ̀jẹ́làdé.***

**Question 9**

**SECTION B: LITIRESO**

***Ṣàlàyé ohun tí ó mú kí Bídèmí máa fi àdá lé ìyá rẹ̀ kiri.***

**Question 10**

**SECTION B: LITIRESO**

***(Kí ni àwọn kókó tí ewì náà dá lé lórí?***

**Question 11**

**SECTION B: LITIRESO**

***Ṣe àgbéyẹ̀wò Àbẹ̀ó gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá-ìtàn nínú ìwé yìí.***

**Question 12**

**SECTION B: LITIRESO**

***Ṣàlàyé ṣókí lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn wọ̀nyí:***

1. *Ọbàkan;*
2. *Opó;*
3. *Àpọ́n;*
4. *Àrẹ̀mọ;*